IMỌLẸ ODODO

Ebun ọrẹ 12s. 6d. fun Musulumi Ododo IWE IMỌLẸ ODODO ti o ni ẹgberun meriin ilokasi eti oro ti ẹsin KIRIYO ati IMALE Owo eyokan tẹle 25s., nisidiyi 12s. 6d. Owo ki o lo nile fun Alukurani Yoruba fi 12s. 6d. ati owo iwon Nigeria 1s, Ghana 2s. ranse si: BOLAJI AKEWUKEWE 32, Offin Road, Lagos Nigeria.

Irohin Yoruba

NO. 717 LAGOS, MARCH 1—MARCH 7, 1959 Kobo Meji (2d.)

LAKAYE ỌRỌ

KI ifẹ ki o wa laiṣẹtan, ẹ takete si ohun ti iṣe buburu, ẹ faramọ ohun ti i ṣe rere.

ỌRỌ OLOTU

Ọbanla ati Azikiwe

IWAJU iku, ẹhin aisan, aarin edidi. Nibo ni a le gbe nibẹ? Kosi ibiti omoluabi le gbe ẹṣẹ le ninu eto iṣelu ti Azikiwe, Olori Alakuko, ti ko ni i bo sinu ijangban. Ni ilu Oyo Alafin-ana gba ọna kan, awọn Oyomisi, ti iṣe ijoye Oyo, gba ọna miran. Ijoba Iwọ-Orun faramọ oro awon ilu ati Oyomisi, nwon si yo Adeyemi loye. Azikiwe so pe ti Adeyemi ni Ijoba Iwọ-Orun ye ki o se, ati pe ko ye ki Ijoba perekelu oro awon Oyomisi rara ni ede kan, ohun ti Azikiwe mba Ijoba / wolowo wi lori oro Oyo fun ni pe nwon fi eti si ohun awon Ijoye Oyo. Ti Oba Alafin-ana nikan ni Azikiwe fẹ ki Ijoba se.

KINI selẹ ni Ilesha? Laipe yi, ipo oye Ọbanla si silẹ. Oba Owa ati diẹ ninu awon ijoye fa ẹnikan kalẹ, awọn ijoye yoku da fa elomiran kalẹ, laisi ohun Owa ninu rẹ. Bi Azikiwe ba jẹ eniti nduro lori eto ati lori oro ara rẹ, nibo ni o ye ki o faramọ ninu oro oye Ilesha? Ibiti Oba Owa ba duro si ni o ye ki o wa. Ṣugbon ẹnu onselu Azikiwe ko je oro kan ti yio wi oro kan. O lodi si Owa ni. Ni Oyo, Azikiwe so pe eniti ko se ti Oba, ti o nse ti awon ijoye, daran. Ni Ilesha, Azikiwe so pe eniti o se ti Oba, ti ko se ti awon ijoye daran. Kini enia le se lati ko aiye Azikiwe ja o? Ewo ni ki a dimu?

KINI otito nipa oro oye Ọbanla ti Ilesha? Oye yi ki iṣe oye iran, bẹẹni ki ise oye idile. Enikẹni ninu omọ Ijesha ni o le je e. Lati aiyebaiye ni Ọbanla ti je igbimọ tabi olubadamoran fun Owa. Idi niyi ti Owa fi ni eto lati igba lailai wa lati yan Ọbanla. Eniti o fẹ imoran ni o sa ni eto lati yan olubadamoran tabi onimoran rẹ. Oba Owa ti o ni eto ati agbara ti pari oro. Ewo ni ti alayonuso. Kini idi ariwo ti Azikiwe npa? Awa kan saara si Oloye Ọbanla J. J. Ibironke. A ti fi oje bo olorisa lowo na, o ku baba eniti yio bọ o.

ỌMỌ OLOYE ỌDUNJỌ GBẸ ỌMỌ AKINTỌLA NI IYAWO

CONGO-SỌ ni nkan bi agogo mejila osan ojo Abameta ti iṣe ojo kokanlelogun osu ti o koja yi, nigbati Oloye S. L. Akintola, Minista Alamojuto Eto Ise Waya ati ti Oko-ofurufu Apapo Ijoba Naijiria ati iyawo rẹ, Oloye Faderera Akintola pe Ase Apejẹ nla si Gbongan Apejo kan ni Ile Igbimo Apapo Ijoba Naijiria l'Eko. Nwon pe Ase Apejẹ yi fun ayo ti omọ won agba obirin, Omidan Omodele Akintola ti Ogbeni Olusoji Atanda Odunjo gbe ni iyawo Arede alarinrin ni St. Paul Church Arran Quay, ni ilu Oyinbo lohun. Akoko ti nwon ngbe iyawo yi ganan lohun ni awon obi omo na nse ase apejẹ yi l'Eko, irohin ko to afojuba ni.

Baba iyawo na wọ agbada ojulowo aṣọ sanyan ati ṣokoto, ati fila lati oke dele bẹ ẹ. Beẹni iya iyawo paapa ro aṣọ sanyan, o we gele sanyan, o si fi sanyan pele. Ọlọla James Robertson, Gomina-Agba Apapọ Ijoba Naijiria ati iyawo rẹ pelu Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijoba Naijiria ati gbogbo awọn Minista Apapọ Ijoba Naijiria ni o wa si ibi ase apejẹ na.

Gbogbo awọn asoju Igbimọ Apapọ Ijoba Naijiria pelu awọn enia jankan-jankan jake-jado Naijiria ni o peju sibẹ, awọn Oyinbo agba onisẹ Ijoba ati awọn Oyinbo onisowo paapa wa sibẹ. Ọlọla James Robertson, Gomina-Agba Apapọ Ijoba Naijiria ni o soro aponle awọn obi iyawo na, ninu oro rẹ, o sọ pe on ba won yo gidigidi fun ti ayo ọjọ oni, o si ṣadura fun iyawo ati oko iyawo pe, ki Oluwa ki o bukun igbeyawo won na.

Lẹhin ase apejẹ ti Gbongan Apapọ Ile Igbimọ Apapọ Ijoba Naijiria ni Oloye Akintola ati Oloye Iyaafin Akintola tun pe ase apejẹ miran si ile won ni Onikan fun gbogbo awọn

(Wo oju ewe kejila)

Aworan yi ni ti aṣeyẹ ti Oloye ati Iyaafin Akintola ṣe fun ti igbeyawo omọ won. Awọn ti o wa ninu aworan na lati ọwọ osi ni Oloye S. L. Akintola, Ọlọla Iyaafin Robertson (Iyawo-Gomina-Agba) Alhaji Tafawa Balewa, Ọlọla James Robertson (Gomina -Agba) ati Oloye Iyaafin Faderera Akintola (Iya-iyawo).

★ ★ ★

Azikiwe ṣọ pe Ọba ko gbọdọ l'ẹnu ni ilu

OSHOGBO.

NINU ọrọ ti Azikiwe ṣọ nihin, ninu ọṣe ti o koja yi, nigbati o wa bẹ ilu yi wo, o ṣe ileri wipe bi nwon ba le dibo fun on ati Egbe Alakuko, ti on ba si le gba Ijoba, eto ti on o ṣe ni lati yọ gbogbo Oba ati gbogbo ijoye kuro ninu onselu. O ṣọ pe on yio ṣe ofin ti nwon ko fi ni lagbara lati ma a da si ọrọ iselu.

Azikiwe ko ṣọ ọrọ yi nihin nikan, o tun ṣọ ọ nigbati o de Ede. Gegebi ọrọ rẹ, bi ohun ti Azikiwe nro ba le bọ si i, kosi oba tabi ijoye ti yio ni ẹnu ninu iselu mọ rara. Oba ati ijoye ko ni i le ni ipo ninu Ijoba Ibile, nwọn ko ni i le je Alaga Kansulu. Nwọn ko ni i le wa ninu Igbimo Asofin ti awọn oloye. Eyiyi ni eto ti Azikiwe ni fun awọn ijoye gẹgẹbi o ti kede rẹ funrarẹ.

Onirohin wa bere lowo ọkan ninu awọn ọba ni agbegbe Ọshun pe kini o ro lori ọrọ Azikiwe yi, Oba na wo titi, o wa dahun pe, "Ohun ti omode fẹ fi eiyele ṣe ni ki i jẹki ọfa omode ba eiyele. Azikiwe fẹ de gbogbo oba ati ijoye mọ inu ago ni, ki nwọn maṣe je nkankan mo ni ilu. Bi owo rẹ ko ba tẹ ago ti yio ko wa si nkọ?"

Ijoye kan ti o tun fi ọrọ yi lọ sọ pe on ro pe were ni Azikiwe npe awọn ijoye. Azikiwe fẹ ki a dibo fun on, ki a le so on di nkan. Lẹṣẹkanna ni Azikiwe tun nso pe bi a ba so on di nkan tan, on yio lo ipo ti a ba fi on si lati so ipo ati ọla tiwa di ofo. Awa ko gọ to bi Azikiwe ti ro. Ori wa pe, a si mo awọn ọrẹ wa.

Ayorisi idije ere-Bọlu afẹsẹgba ilu Oyinbo ti nwọn gba ni 28:2:59

UK FOOTBALL RESULTS

ENGLISH F.A. CUP

SIXTH ROUND

Aston Villa	0	Burnley	0
Blackpool	1	Luton T.	1
Nottingham F.	2	Bolton W.	1
Sheffield U.	1	Norwich C.	1

LEAGUE DIVISION I

Arsenal	5	Manchester U.	2
Birmingham C.	3	West Ham U.	0
Everton	2	Tottenham H.	1
Leeds U.	1	Portsmouth	1
Leicester C.	0	Newcastle U.	1
Manchester C.	1	Wolverton W.	4
Preston N. E.	1	Blackburn R.	2

LEAGUE DIVISION II

Bristol R.	2	Brighton	0
Derby C.	3	Grimsby T.	0
Fulham	1	Bristol City	0
Leyton O.	2	Liverpool	2
Lincoln C.	4	Cardiff City	2
Scunthorpe U.	0	Middlesbrough	3
Stoke C.	2	Barnsley	1
Sunderland	1	Huddersfield T.	0
Swansea T.	3	Rotherham U.	0

LEAGUE DIVISION III

Bradford C.	1	Reading	2
Brentford	5	Tranmere R.	2
Chesterfield	2	Q. Park R.	3
Halifax T.	1	Southend U.	0
Hull City	3	Stockport C.	1
Mansfield T.	3	Doncaster R.	1
Newport C.	1	Bury	1
Notts C.	1	Rochdale	1
Southampton	0	Bournemouth	0
Swindon	3	Plymouth A.	4
Wrexham	2	Colchester U.	0

LEAGUE DIVISION IV

Aldershot	1	Chester	3
Barrow	2	Bradford	1
Carlisle Utd	0	York City	0
Coventry City	3	Crewe Alex	2
Darlington	4	Southport	0
Exeter City	3	Northampton	4
Gateshead	1	Crystal Palace	3
Gillingham	5	Wrexington	1
Millwall	4	Watford	1
Oldham Ath.	0	Port Vale	2
Shrewsbury T.	3	Torquay Utd	0
Walsall	0	Hartlepools U.	0

SCOTTISH F.A. CUP (THIRD ROUND

Celtic	2	Rangers	1
Dunfermline	2	Ayr. Utd.	1
Hamilton A.	0	Kilmarnock	5
Hibernian	4	Partick T.	1
St. Johnstone	1	Aberdeen	2
St. Mirren	3	Motherwell	2
Stirling A.	7	Morton	1
Third Lanark	3	Alloa Ath.	2

SCOTTISH DIVISION I

Dundee	2	Clyde	1
Queen of S.	2	Falkirk	1
Raith R.	3	Airdrieonians	0

SCOTTISH DIVISION II

Albion R.	1	Cowdenbeath	1
Arbroath	2	Brechin City	0
Dumbarton	2	East Fife	2
East Stirling	1	Queens Park	2
Montrose	0	Forfar Ath.	4
Stirenaer	2	Berwick R.	1

OTHER MATCHES

Sheffield Wed	4	Charlton Ath	1
Ipswich T.	1	Hearts	0

Results.

A daba ma le mu u ṣe ni ẹgbẹ Alakukọ

KINI Azikiwe fẹ wa sọ fun wa? Ẹgbẹ Azikiwe ṣeleri pe bi a ba dibo fun awọn ni odun 1954 awọn yio din owo-ori ku. Awọn miran tile leri ninu awọn Alakukọ pe awọn yio pa owo-ori re patapata. Iro funfun ni eyi. Ti ilu wo ni owo-ori ti din kobo kan lati igba ti a ti dibo fun Ẹgbẹ Alakukọ ni odun 1954? Koi ti i din kobo ni Onitsha, ilu Azikiwe paapa. A ko gba iro mọ.

Emi ni,

VICTORIA OYINLOLA.

Oshogbo.

Iwe si Olotu Irohin Yoruba

Kini Ẹgbẹ Alakukọ ṣe si ọran Ijọba Ghana?

NIGBATI mo gbọ ohun ti Ijọba Ghana ni oju awọn ara Naijiria ti nwọn wa ni Ghana ri, inu mi baje pupọ. Inu mi si wa a dun nigbati mo ri i ka ninu Iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ kini osu yi bi Ẹgbẹ Ogbomoṣho Parapọ ti se mu oran won na lọ si'waju Alhaji Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba Apapo Naijiria. Mọ gburo atunse ti Oloye S. L. Akintola, Minista Alabojuto Iṣe Waya ati Oko Ofurufu se lori oran na.

O ya mi lẹnu pe, Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ati Ẹgbẹ OLOMI (NPC) ko da si i. O ya mi lẹnu pupọ. Emi ko ni ero pe nwọn le fi gbigbọ s'alaigbọ nipa oran pataki bayi. Irufe iwa bayi ko dara rara. Sugbọn o dunmọ wa lati gbọ pe Dokita Nkrumah, Alakoso Ijọba Ghana ti se ileri lati ri i pe Ijọba on yio ma a se dada si awọn ara Naijiria ti nwọn wa ni Ghana.

Emi ni,

MUYINDEEN BOLAKALE.

Ikorodu.

Ara Agbọwa nfẹ iranlọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun

INU mi yio dun ti e ba le gba mi laye lati sọ ọrọ edun ọkan mi sinu iwe nyin ti ogunlọgọ awọn enia ma a nka kakiri aiye. Oluwa yio tubọ ma a ran nyin lowọ o.

Ti a ba ko ile fun omọ eni, a o fi ilẹkun meji si ile na fun un ni nitori akamọ. Ti a ba si ileku niwaju ile a o tun si ilẹkun ni ẹhinkule pelu. A dupẹ lowọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fun ilẹkun ona Eko ti nwon si fun awa ara Agbọwa. Ki Oluwa ki o tubọ ran Ijọba na lowọ. Amin.

O ku ilẹkun ẹhinkule ki e si fun wa pelu. Iyen ni Ito Eke. Omi Ito Eke ni Ikin ka wa mọ pupọju, bi oko ba dide ni Eko ti o ba de Agbọwa o pari niyen. E jowọ, a be nyin pupọ, ki e fi oju anu wo wa, ki e ba wa si ilẹkun ẹhinkule silẹ o.

Emi ni,

THOMPSON AKEJU.

Imọba Ijọba Ikorodu.

Ina esisi ki i jo ni lẹmeji

AZIKIWE be wa ni odun 1954 ki a dibo fun omọ egbe on. Ko si ohun ti Azikiwe ko se ileri tan pe Egbe Alakukọ yio se bi a dibo fun un. Kini a ri gba lati ọjọ ti a ti dibo fun Kola Balogun? Emi ko ri nkan na. Ina esisi ki i jo ni l'emeji.

Emi ni,

SAKA KASALI.

Isale Oshun, Oshogbo.

A da ija silẹ ni ẹgbẹ Alakukọ

LATI igbati awọn Alakukọ ti ki owọ bọ oro wa ni ijangbọn ti'wọ ilu yi. Baba di ọta omọ, iya di ọta baba. Jagidijagan upọ si i. A ko ri ami woro nkan rere kan ti a ri gba lati odọ awọn Alakukọ wa. Ko si ohun ti o ya wa lori ti a fi tun le dibo fun Alakukọ mọ.

Emi ni,

BUSARI FARAYOLA.

Iwo.

Ẹgbẹ Alakukọ ki i gb'omọ ki o ye

EKỌ-OFẸ fo mọ Azikiwe lori ni ile Ibo. Banki di ejọ mọ Azikiwe lọwọ. Ogunlọgọ ijoba ibile ni o ti fo mọ awọn Alakukọ lori. Ẹgbẹ Alakukọ paapa nfo lọ mọ Azikiwe lori. Kini Azikiwe fi owọ ba ri ti ko fo mọ o lowọ? E jeki a fiyesi ara ki Ẹgbẹ Alakukọ ma ko okuta ba wa.

Emi ni,

ALABI KASUMU.

Ado Ekiti.

Nje aiye nyi bi ogo ni?

OLOTU jowọ gba mi laye lati bere pe otito ni aiye nyi bi ogo ati pe bi ile ba su nibi kan, a ma a mo ni ibikan ninu aiye yi na?

Emi ni,

B. A. ASHIRU SHAKI.

Niamey Niger F.W.A.

IDAHUN IBERE OKE YI

Otito ni pe aiye nyi bi ogo, ti ile ba su ni iha odọ wa ni Afrika, imole a wa ni Amerika, ti ile ba si su ni Amerika imole a de si odọ wa ni Afrika.—OLOTU .

Irohin Yoruba

ORỌ OLOTU

Azikiwe nfẹ saba le ẹyin-ẹlẹyin

NIGBATI Dọkita Azikiwe, Olori Egbẹ Alakuko ati Alakoso Ijoba Ipinlẹ Ila-Orun fẹ wa si Ipinlẹ Iwọ-Orun lati wa polowo egbẹ rẹ fun idibo ti nwon fẹ se lati yan asoju si Igbimọ Asofin Ijoba Apapọ Ijoba Naijiria, o ranse si Oloye Obafemi Awolowo, Olori Egbẹ Afenifere ati Alakoso Ijoba Ipinlẹ Iwọ-Orun pe ki o fi aye gba on fun gbogbo ipade ti on yio se yika awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun.

PẸLU ifẹ-inu-rere si enia gbogbo ni Oloye Obafẹmi Awolọwọ fi ko iwe ransẹ si gbogbo awọn asiwaju Egbẹ Afẹnifere kakiri awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun pe ibikibi ti Dokita Azikiwe ba fẹ se ipade ki nwon fi aye gba a lati so ti enu re fun awọn alatilehin re ti ko fi ni si ija tabi idarudapọ ninu ipade re.) si tun kilo fun won bakanna pe bi ọrọ re tile je ikoro leti won, ki nwon mase da a lohun.

EGBẸ Afenifere ni Oloye Awolọwọ je Olori fun, enikeni ni o si fẹ rere fun, ko ba enikeni sota afi awọn ti o ba fẹ ba a se ota nitoriti nwon ko fe otito, ti nwon feran okunkun ju imole lọ, ti nwon si nfi okunkun pe imole, ti nwon nfi imole pe okunkun nitori ise iselu won buru. Nitorina, a bẹ gbogbo enyin omọ Egbẹ Afenifere ki ẹ ma a tele anere ti Oloye Obafemi Awolọwọ yi nipa pe ki a ni ife omonikeji wa, ki a si kun fun otito ninu gbogbo ise iselu wa nitoripe "nuro nginivi ete ni i gbehin re". Evi ni o nda awon Egbe Alakuko laamu.

KINI Azikiwe fẹ ri sọ fun won ni Ipinlẹ Iwọ-Orun pe egbe on se sibe ni rere, kini pataki ise ilosiwaju ti Ijoba Egbẹ Alakuko se si Ipinle Ila-Orun nibiti nwon gbe nse Alakoso? Eniti o ba so pe on yio ya ni ni ewu wọ, a o sa wo iru eyiti on na wọ sorun. Nigbati Azikiwe ko le ri akosile kan gbe jade nipa ilosiwaju ti Ijoba ti nse Alakoso re se si Ipinle Ila-Orun, kini a fẹ so pe on o tun se ti nwon ba dibo funo n wole Igbimọ Apapọ Ijoba Naijiria?

Se gbogbo ise ilosiwaju ni orisirisi ti Ijoba Awolowo ti se kakiri ilu Ipinle Iwọ-Orun ni o nfẹ so pe ise owo on ni? Eniti yio ba sa je ogun-kogun yio pa itan-kitan. Ki ise oni re ni ti i fe ma a "saba -le-eyin - elẹyin", nitoripe gbogbo eto rere ti Egbe Afenifere ba gbe kale, a ma a so pe on ni on ti fi ilana re sile, oju ki I si I ti i... Ti Azikiwe ko ba ni itiju lati ma a puro fun enyin ara ilu Naijiria, ohun ti e le se fun un ti yio ka a lara ni pe, e ko gba iro re mọ.

Egbẹ Ilupeju Omọ-Shepeteri se ipade ajodun

NAVRONGO, GHANA.

NI ojọ Ojobọ ti ise ogunjọ osu kokanla odun ti o koja yi (1958), ni nwọn Egbẹ Ilupeju Omọ Shepeteri ti o wa ni Oke-Okun se ipade ajodun ni ilu Navrongo. Nigbati ojọ ipade na ti ku ola ni ese awọn ikọ ti o wa lati ilu kookan ti pe sibe.

Ni kutu-hai aro ojọ na ni nwọn ti lọ ji ki Oba ilu na ki nwọn to wa bere ipade na, ohun ti o se pataki julọ ti nwọn kokọ yanju ninu ipade na ti awọn asiwaju egbẹ na meji ti o ti nse Egbẹ Alakuko, ti awon omọ egbẹ yi pe ko dun mọ awon ninu afi ti nwọn ba kọ Egbẹ Alakuko silẹ ki nwọn siwọ Egbe Afenifere.

Inu wọn si dun pe ninu ipade na ni awọn mejeji Ogbẹni Salami Aroyewon (Alaga-egbẹ) ati Ogbẹni Asiru Omolere si pinnu ni ojọ na pe, awọn ti yọ-wọ-yọ ese ninu Egbẹ Alakuko (NCNC) awọn si ti wọ Egbẹ Afenifere (Action Group) gbogbo wọn si ho fun ayọ, nwọn gbe owọ soke ya foto lati fi han pe awọn nyombo Egbẹ Afenifere (Action Group).

Awọn omọ Shepeteri ti o wa ni ile Egbado ati Ibadan ran awọn ikọ meji wa, Ogbẹni Z. O. Adegbite lati Egbado ati Ogbẹni Joseph A. Omitẹbọ lati Ibadan. Ipade na si yan Ogbẹni E. B. Alao ni asoju awọn omọ Shepeteri Ghana. Nwọn si yan Ogbẹni K. P. Ola ni akọwe-egbẹ dipo Ogbẹni Lasisi A. Ade. eniti o ti nse bọ lati odun kesan, nwọn si fi ipade kewa ti nwọn yio se ni odun ti mbọ (odun 1959 yi ni) si ilu Bolgatanga.

Awọn ilu ti o yan ikọ wa silipade na ni Tamale; Bole; Tuna; Lungni; Gushegu; Bolgatanga; Walewale; Nandom; W. A. Kumasi ati Owagadongon.

Aseyisamodun o.

Ona ti e o si gba pe e ko gba iro apatunpa re mọ nipe ibikibi tabi ni ilu-kilu ni Naijiria ti Egbẹ Alakuko ba ti yan enia sode lati dibo fun, e ko won sile, e mase dibo fun won. Bi e ko ba se be e fun Egbẹ Alakuko, omugo ni nwọn yio maa pe nyin pe e ko le gbon lailai, eniti o ba si nso fun ni pe kini a le se ni a nse e han.

"ALAGBA ti yio tẹle tutu yio da omi siwaju". Azikiwe nfẹ ki nwọn o dibo fun on ati awọn omọ egbẹ on sugbon nwọn ko sise rere kan tẹle ti ara ilu le ri fi dibo fun won. Nigbati Azikiwe ti mọ pe egbẹ on ko ni ese nile mọ ni o se lọ dapọ mọ Egbẹ Olomi (NPC) ati NEPU "Okan-un-kanun ni kanun" ni idapọ awọn meteta je Egbẹ Oselu meteta won-yi ko ni akosile atata kan ti nwọn le se ogo le lori pe, awọn se fun ilosiwaju ilu Naijiria. "Iro nparo fun'ro" ni gbogbo won. E ko won sile, e mase dibo fun won.

OVALTINE

Nfun awọn omọde ni idunnu ati alafia

FIHAN pe pẹlu agbara idan ni Surf fi nfọ aṣọ mọ

1 Sa f'oju fun aso re po ninu omi pelu SURF

Ma sopo gboo, ma sopo run un. Bi awon aso na ba riri gidigidi, fi won sile ki nwon re dara-dara ninu hiho SURF na fun wakati kan ni akoko.

2 Wo o bi gbogbo re ti mọ gaara si

Ati funfun ati alawọ orisirisi ni yio jade ninu hiho SURF na pelu mimọ laulau—MIMỌ TAARA.

3 Waa le ri bi eeri ti nyọ jade

Bojuwo omi dudu na ki o to o daa nu. Beni—agbara idan SURF ti yọ gbogbo eeri jade: awọn aso re si mọ ju ti atijọ lọ.

ESAN KOGB'OGUN

Ẹni ba ṣe rere ni yio gb'ẹsan rere (10)

EMI Erukobodo se ileri l'ose to koja wipe, bi Eleda ko ba ti gba emi mi, ninu ose yi ni ngo so iru ohun ti Oreasekupani tami lore ki nto fi ilu Arikogbon orun awon elese sile. Ohun ti o fi ta mi lore na, o wu mi ju wura ati fadakalo, o si wu mi lati fi ohun na han agbaiye nitoripe, ohun ti o le se t'omode t'agba wa ni anfani ni.

ITALORE LATI OWO ORE ASEKUPANI

Iwo ore mi Erukobodo ko to ki ngma fun e ni ohun pataki kan fun igbolya re ti o gbe o de ilu Arikogbon orun awon elese yi, nko ni fun e lowo, beni nko ni fun en i ohun ose ile aiye, bikose wipe ki nfun o ni alaye ohun ti o ngmu adura eda gba nile aiye ati eyiti o mu eda de orun alafia.

Alaye mi na fun o ni wipe, ki o ti ojo oni bere si ma a hwa rere, ki o si ma a wa alafia fun omonikeji re, bi ohun kan ba je ohun edun okan re tabi idamu kan lo de ba o, ri i wipe o wa ni imototo ki o to ke pe Eleda re pelu inu kan, ni alaikose iyemeji. Oluwa yio tewo gba adura re. Lati ojo oni lo, mase da ara re po mo awon alai mokan ti nwon ko ni igbagbo si Eleda won, ti nwon ma nro wipe adura ko le yi ohun buburu pada si rere, tabi awon ti o nlero wipe, Ayanmo tabi Kadara mbe.

KADARA KAN KOSI

Emi Ore-asekupani yio so fun iwo Erukobodo ni asoye wipe kosi ohun ti nje kadara rara, ohun ti o mbe fun eda ninu aiye ni awon eni ti eda ba ka kun olowo tabi olola, ti nwon ko lati pa ofin Eleda won mo, nitoripe ni ero won nwon ti tobi pupoju loju ara'won. Olorun a si pa basira owo ati ola na mo won lara, a si yi won pada di atoroje, bi eniti a ti ka kun atoroje, bi o ba je on ni o pa ofin Eleda re mo, ti o si nsin Eleda re l'ona toto pelu ara mimo ati adura atokanwa, Olorun Oba, a se eyi t'owu a si pa buburu re da si rere fun.

Gbolohun yi ti han si gbogbo awon eni mimo ninu ero Olorun ti o so sinu akosile Re wipe—Bi o ba wu On Olorun, a gbe Talaka jade lati inu erupe, b'o ba wu U" a gbe alagbe lori ori akitan a si ko won jo pelu awon Omo-alade. Fun alaye ero mi yi, le wo Samuel ori 2 ese 7 titi de 8, nitorina ko si Ayanmo tabi Kadara kankan fun eda laiye, bi ko ti si kadara fun eda l'aiye to ko si eda kan ti yio ma a ke pe Eleda re pelu inu kan ati wipe, ki o si ma a pa ofin Re mo,ti "Oba Arinu r'ode Olumo okan ko ni rojo ibukun Re sinu ile oluware.

Lati ọwọ "Erukobodo" Eko

ADURA YESU YESU

Sugbon, emi Ore-asekupani yio tun so ni asoye fun iwo Erukobodo wipe, opolopo eda ni nwon maa fi enu ara won fa ohun buburu si ori ara won, ti nwon ma nso wipe, awon nse adura, eyiti o je wipe ona ti ko to ni nwon ngba se adura, ti nwon a si ma a wipe adura awon ko gba, nwon ko mo wipe adura yesu-yesu, adura ori ahan, tabi ki nwon ko Adura po mo Ebo sise, nipataki opolopo eda ni nwon nse adura, ti nwon tun nhu iwa aito, iwa odale, iwa ki a f'oju feni ki a mase fi okan fe enia d'enu, iru iwa ti emi Ore-askupani ti bu koja sehin, ti mo fi ri gbogbo ohun ti mo nrohin re fun iwo ore mi Erukobodo loni yi.

Eniti o ba mo iwonyi ni ese, ti o si je wipe nwon ko le ji l'ojo kan ki nwon ki o mase huwa ese yi ti iru awon eni be e si fun wa mi, sugbon emi ki yio da fun, nwon o se aferi mi ni kutu kutu, sugbon nwon ki yio ri mi.—Owe ori 1, ese 27.

Sugbon, eda ti o ba pa ofin ti Olorun mo, ti o si ni igbagbo si Eleda re, ti o si tun nsin In l'ona ti o to ati wipe, o tun nse adura na pelu sara anu fun awon alaini, ni alai ko se iye meji were-were ni adura re yio gba.

SARA TO DARA FUN ADURA

Ohun ti emi Ore-asekupani tun fe fi ye iwo Erukobodo ni wipe, sara sise fun adura o dara pupo, sugbon orisirisi ona ni eda ile aiye ngba nse adura, awon kan wa, bi nwon ba je, ti nwon ba yo tan, nwon a d'ana sara sile, nwon a fe ki aiye le ri awon, nwon a ko olola, olowo ati gbajumo ilu jo, nwon a ma je, nwon a ma a mu, nwon a da aro pomo sekere, nwon a ma a jo a jo la'gun, bi nwon ba ri talaka tabi onibara larin won, nwon a le e sonu, nwon ti gbagbe owe awon ti o sewa sile kan ti o so wipe:—"Eniti o ba nse ki aiye le ri on, ai ko ni ri i mo rara ni yio gbehin re."

Beni sara ti Olorun nfe ati eyiti o le tete mu adura eda gba, on ni sara sise fun

(WO oju ewe kesan)

Ọṣẹ ifọṣọ ti o fẹran julọ

NI O WA NISISIYI NINU IWE TITUNU TI ON NDAN YI!

—o dara julọ fun fifọ GBOGBO nkan!

Fun didan awon aso funfun ati eun awon aso eloriiriri-awo-li amoolo oluran didan le kan de yipo, ma a lo ose Sunlight Soap nigbagbogbo!

Idahun Alfa Bọlaji Akewukewe si ọrọ Evangelist Akande

AKANDE ṣọ pe Bibeli ko awọn ti eko rere ninu Timoteu pe "Iransẹ Oluwa ko si „bodo ja," ṣe Jesu ko ha nse iransẹ Olorun li o ṣe so ninu Matteu 10 ẹṣẹ 34-37 pe, "E maṣe ro pe On wa ran alafia si aiye, emi ko wa ran alafia bikose ida, On wa lati ya baba ni-pa si omọ rẹ, ati aya-omọ si iyaa-oko rẹ, gbogbo ara ile enia (kio si di) ota rẹ, ati nibomiran (Luku 12 ẹṣẹ 49-53) bayi pe "E maṣe ro pe alafia ni On wa ran si aiye ' eeko, kia sa kuku ṣọ pe iyapa, ina ni on Jesu wa fọn si aiye, kini On si nfẹ bi a ba ti da ina? Atako oro Bibeli pupọ bawonyi li o mu esin Kiriyo su olotito ti Kiriyo fi nkigbe ninu iwe irohin pe Imole ngbile mọ awọn lowo otito inu Alkuriani ni ko je ki iro pipa ti Akande ati awọn Kiriyo elegbe re nipa esin Imole ranlẹ rara, ti ereke-eebu won ko si fi ran nkankan rara. ... ...

Akande ṣọ pe ninu Matteu ni Jesu gbe ṣọ pe "E wa sodọ On, enyin ti a di eru wiwuwo le lori, On yio si fi isimi fun nyin".

Bi oro inu iwe Bibeli ko ba je ohun ti nko are okan ba olufe ododo, kinise ti Bibeli so ni ede Oyinbo (King James Version) Heberu 4 ẹṣẹ 8.....bayi pe, Jesu iba fun won ni isimi ni, on ki bati soro miran lehinna ki nwon to yi Jesu na si Joṣua ninu Bibeli ede Yoruba, kiriyo ṣa nyi kan laiye won sa a, eru wiwuwo na ko ni gbese owo kilasi ti nwon so di owo tulasi ti nwon nko si eniti ko ni lọrun bi?

Alkuriani so ni Surat 65 ayat 7 pe, "ki eniti o ni pipo ti aye arisiki gba ṣe to bi Olorun ti gba a laye to, atipe eniti Olorun fi osuwon si iba ohun ti o ni ki o se mọ ni bi On Olorun ti gba a laye mọ". Eyi fihan pe esin Imale gan an ni ajaga re fuye nipa aikowe gbese si talaka lorun, dajudaju eru wiwuwo ni owo tulasi ti Kiriyo npe ni owo Kilasi, ati owo abela ati owo ororo ati owo ti nwon gbodo ṣe alaiju simu apoti isura nigbati awọn Kiriyo ba njo yi apoti na po. Eniti o lowo ati eniti ko ni owo lo si kiko ile Olorun, bakanna ni nwon leto ati se isin ninu Mọsalasi.

Akand so pe Jesu so pe onirele okan li On, nje mo bere pe, si iya Jesu ni Jesu ha je onirele bi, nipa pipe ede ailoye ti o fi so fun iya re ni Johannu 2 ẹṣẹ 1-4 pe "kinise temi tire obirin yi? Akande so pe Kristiani ki nfa ijangbon, awọn kinse arufin, esi temi ni pe ko si ona ti awọn Kiriyo wonyi ko fi je arufin, nwon je arufin nipa aibikita fun ofin isin Olorun ti o wa ninu Bibeli, bi ti iwe ọwọ ati ẹṣẹ (Aluwalia) Eksodu 30 ẹṣẹ 17-21 ati ori 40 ẹṣẹ 30 -31, ati Johannu 13 ẹṣẹ 3-16, bi ofin igbowo soke, iteriba ati iforibale ninu isin ti a npe ni irunkiki, wo Nehemiah 8 ẹṣẹ 1-6.

Bi ofin aigbodo je eran eledẹ, wo Liffittiku 11 ẹṣẹ 7-8. Bi ofin igun petesi lo fi ohun rara pe ipe ki nwon dide sin Olorun ati siso lori petesi na pe okansoso li Olorun li a npe ni irun pipe. Nehemiah 9 ẹṣẹ 4-6. Bi Lawani wiwe, Sekariah 3 ẹṣẹ 3-5 ati Ezekieli 24 ẹṣẹ 22 ati beebee; bi odun Easter ti o je ti awon aborisa wo iwe Imole Ododo oju ewe 184 ori 107 ti yio so fun e pe ki owo "Bibeli Student Companion ti William Nicholson ni oju ewe 307; tabi ọjọ kedogbon osu December ti o je ọjọ ibi oba aborisa ti e so di ọjọ ibi Jesu nipa amọlọ ọjọ bi Jesu mọ.

Bi al si eri agogo siso mọ oke fi pe enia ninu Bibeli. bi al si eri fifi owo sofo nipa racket yiyin, owo ti nwon iba fi fun talaka li onje, wo bi Olorun ti nife si bibo talaka to ni Isaiah 58 ẹṣẹ 7-8 gbogbo ofin wonyi ni Kiriyo ti gbeju si ehin won patapata wo (Nehemiah 9 ẹṣẹ 26). Bi o ba si je pe ofin ti ijoba aiye ni Akande ro pe awọn Kiriyo ki nru ni on ṣe pe Imale ni arufin ni, ki Akande wo iwe Irohin **Daily Service** ti ọjọ ketadilogun osu March 1958 oju ewe keta ati **Irohin Yoruba** ti ọjọ kerinlelogun osu na ti o so pe Kiriyo li o poju li ogba ewon, aborisa ti iwe na so pe o wa li ogba ewon li odun kan je 9,000 egberun mẹsan, Imale 7,000, egberun meje pere, Kiriyo si je 24,000, egberunọna merinlelogun, tori idi eyi Akande paro lati, ma jewo pe awon Kiriyo ni arufin ti aiye ati torun.

Akande so pe awọn ki nfi Bibeli ti awon pa enia, esi temi ni pe, iwe kefa ati ekeje ti Mose ti awon Aladura nlo ti o ko nyin bi e ti se nlo Bibeli fi pania, o ko nyin lati ma a ka Orin Dafidi 109 ẹṣẹ 1-14 fi pania, lo ka wo, iye igbati o so pe ki e ka a le ota yin lori ni emi ko ni ranyin leti, emi ko si ni ran nyin leti awon ohun ti o ni ki e pese re alle siwaju nyin ki e to ka a pelu. Asiri nyin ti tu si wa lowo pupọ koja ki iru Akande tun ma a pa iro tan waje. Numeri ori 5 ẹṣẹ 11-29 ni e ma a nlo fi mu inu obirin wu ti itan re yio si ra pelu, abi ewo ni Akande fe lati pe ni ise rere fun wa ninu gbogbo iwonyi.

Akande lo je alaigbon t'o fi tubo nfin awa Musulumi miran, mo ti so fun un tele pe eyiti emi pelu re ko si yi ni awọn Kiriyo aiye yio fi fa Akande leti pe ko seun, boya Akande ro pe inale ni mo, ki Akande niso nile Akande paro pe bi Imale ati Kiriyo ba pade, Imale li o ma nda ariwo alle, eyi tun je iro pelu, nigbati emi pelu Akande pade fun ise asoye oro Olorun po li odun 1951, Akande li o fi ilu lilu da ariwo sile ti o fi da eto ojo na ru lakoko pade mi; ti ilu lilu ti je nibiti a gbe fe so asoye oro Olorun no? Ara iro ti a so pe o dun pupo lenu ati lowo gege Akande ni fi fi kowe na ni-wonyen.

Ki Akande wa si gbangba oju taiye li Eko ki o wa wo bi Imale ti ni eto alafia nipa siso asoye oro Olorun ni waasi odọ mi. Akande sa ti sa fun ipe ti awọn Egba omọ Lisabi pe si i pe, ki o wa pade mi nibe nijosi. Akande so pe okan ninu ohun ti o je ki on pe Annabi wa mimọ Muhammodu ni arufin nipe Alukuriani so fun awon Mumini ti nwon gba Olorun ati Annabi gbo ni Surat 4 ayat 3 pe, nwon ko gbodo ni ju ava merin lọ. Akande so pe Momodu si ni aya mẹsan Akande fi han pe ko si ayat ti o gba Momodu li aye a ti se be e ninu Alukuriani lati oke dele, eyi je ogidi iro pipa pelu, ohun ti o si sun Akande si iru iro yi ni nipa ni aini imọ Alukuriani jinle.

Surat 33 ayat 50-52 ni Olorun gbe so fun Annabi wa bayi pe:—

"Iwọ Annabi,—A ti se awọn obirin re ni haliali fun e, awọn eyiti o san owo le lori ati awon eru ti owo otun re ni ikawoni ninu awon ti Olorun fi fun e, omobirin ti arakunrin baba re ati omobirin ti arabirin ti baba re ati omobiin ti ara -konrin iya re ati omobirin ti arabirin ti baba re ati ati omobirin ti arabirin iya re ti nwon se isikuro ni (Mẹkka lọ si Medinat) pelu re, ati Muminibirin ti o ba fi ara re fun Annabi, atipe bi Annabi ba fe lati fe fi se aya, ni (iyonda) isalesa fun Iwọ Annabi nikan laije be e fun awon Mumini yio ku. A ti mọ ohun ti a se ni oranyan fun awon (ni Surat 4 ayat 3) nipa obirin won ati nipa awon eru ti owo otun won ni ikawo ni, ki o ma ba si alebu ibawi fun e. Allah si je Alaforijin ati Alanu".

A ri pe oro Olorun ninu ayat Alukuriani yi so pe ko si laifi alebu ibawi fun Annabi lati fe awon obirin pupo to bi ayat adota yi ti yonda. Ayat 52 ni Olorun so pe lehin awon wonyi ni awon omiran ko je alaifi fun e, lati fe mọ, o si so pe Annabi ko ni eto lati se inaaro obirin rara ninu eyi-ti on ba ti fe. beli awa Mumini ti a je omolehin Anabi ni eto ati paaro obirin (Surat 4 aya 19), aya 52 ti Surat 33 na fi kun oro re ne, "ewa awon obirin miran ki ba tile te Annabi lorun, sibe na awon obirin re wonyen nikan sa a ni a gonda fun e mo." Ko si eriban ninu Alukuriani ati Adiel ti o se ne "Annabi ni obirin elomiran kankan ni ale rara ri."

Akande se asise leti ka Aditatu iyawo Annabi ti o ti ku mọ awon obirin ti o wa li oye otito Annabi ni eru ti o nje Zaidu, ki nse omo odo re, eru ni Zaidu je ko si eri kan ninu Alukuriani ti o so pe Annabi iba iyawo enikan-kan ri ko si ibiti Alukuriani ba da Annabi lebi eekan ri bi a ti ri ti awon ti Jesu so pe ki a gbe ran si lenu (Matteu 23 ese 1-3) ti da Jesu ati awon omo ehin re lebi ni (Matteu 12 ese 1-4) nipa pipe Akivesi Jesu si evi ti ko ye ti awon omo ehin re nse nipa viya oka-çloka je ti Jesu paapa si gba pe awon ko ni. nwon koko se iru ohun aito be e, ti o si fi ise aito ti Dafidi se akawe ti nwon pelu ni ese kata. Bi o ba je ese ni fun Annabi a ba ri ibiti Olorun iba ti ko Muham-madu bi a ti ri eri ibiti Olorun ti ko Jesu, lenu Jesu funra re ni (Matteu 27 ese 46) nibiti Jesu mbere ohun ti o se ti Olorun fi ko on.

Alukuriani Surat 93 ayat 3 tile fi ijeri fun Annabi wa pe Olorun ko ko o (Muhammadu) beni ko si korira re rara. Ohun pa-

(Wo oju ewe kejọ)

M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)
Ina dé, òkùnkùn paradà. M.B.T dé, òkùnrùn jọ lọ. Èjè dúdú sáré, òyì pòsèsè. Alá buburú wọ gbó. àìlèsùn r'èhìn-èkùn. M.B.T. fọgùn-èjè ti nmú ni jeun b'ikán, amú ni yàgbé bi òkùn, amú ni tọ bi àkéré. Abíwéré f'áboyún, agbèjèdi fawọn abíyamọ. Ahọn-dúdú, èsè-wíwu ati àìyá-jíjá ko si pẹnití nlo o.
4s. 6d. pelu owo-oko lọtọ.
ARADAN STORES P.O.Box 2
EBUTE-METTA.

Nigbati awọn ọrẹ ba pade —
Ohun kan ṣoṣo ti o darajulọ ni
BLACK PRINCE
Schiedam Aromatic Schnapps
Wa a gba pe awọn ọrẹ wonyi nwo pelu ifera ati okan ti o ni jtẹlọrun dada—be e ni iwọ na yio ma a wo bi o ba mu BLACK PRINCE. ti o lokiki yika gbogbo aiye gegebi ohun ti mu ti o dara ti ko si l'ewu ninu, o se e gbekele, o si je ogun atejese ti a nfun ni lagbara.

Aworan yi ni ti igbati Ogbeni Afuye gbe omọ-iitun ti iyawo re bi fun un dani ti on ati iya omọ na si nwo o ni ojọ ikomọ omọ na ti nwọn se ni ọjọ Aiku ti ise ojọ kerindilogun osu kini odun yi ni 5. Saba Court l'Eko, oruko ti nwọn sọ ọ na ni Shakiratu Olatowun.

ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

Lati Ọwọ E. Alabi Thompson

SUGBỌN a rí a ti ẹgbẹ nitori irẹkọja wa, a pa a ti ara nitori aisedede wa; ina alafia wa wa ti ara rẹ, ati nipa ìna rẹ ti a fi mu larada.—Isaiah 53 ese 5.

1. Eni 'kanu!—eniko
T' a npe Omọ Olorun
T'o wa gbu ẹlẹṣẹ la
Alleluya! Ologbala.

2. O farada eleya
A da lẹbi n'ipo mi
Eje rẹ setutu fun mi
Alleluya! Ologbala.

3. Oto's elese ni wa
Alailabawon fi On
Nje l'oto l'O setutu
Alleluya! Ologbala.

4. A gbe ko sori igi
O ke pe, o ti pari
A gbe ga lorun n'sisiyi
Alleluya! Ologbala.

5. Gba!' Oba Ogo ba de
Lati m'emi Rẹ re le
Ao ko orin yi l'otun
Alleluya! Ologbala.

ITẸN ORIN NA

Eniti o ko orin yi je okan pataki ninu awọn olorin adiẹnu ni ilu Amerika, oruko re a ma a je Phillip Bliss. O ko orin oke yi fun iranti ijiya Jesu lori Agbelebu. Phillip Bliss ku ainotele, nigbati o rin irin ajo lori oko oju omi; oko danu o si nse aniyan lati gba on ati iyawo re la ki olojo to de ba won.

Ẹgbẹ Akinmọrin Oke-Okun ṣe ipade

SALTPOND GHANA.

NI ọjọ Aiku ti ise ojo kẹrinla osu kejila odun 1958 ti o koja yi ni awọn omọ Egbẹ Ilosiwaju Akinmorin ti a npe ni "Akinmorin Imporvement Union" Oke-Okun se ipade kan ni ilu yi. Ogbeni Koleosho ni Alaga, Ogbeni Filipi Akingbade ni Gbakeji re, nwon si fi adura si ipade na. Pataki ohun ti nwon se ipade na fun ni lati se asaro lori bi ilu won Akinmorin yio ti se ni ilosiwaju.

Nwon da imoran pe, o ye ki awon ke pe Ijoba Ipinle Iwọ-Orun ati Ijoba Ibile Oyo ki o se iranlọwọ fun awon lati ni Ile-itoju aboyun ati ti awon alabiyamọ ati Ile-itoju egbo awọn omọ Ile-iwe. Ninu awon ilu pataki-pataki ti o wa ni Ekun Oyo, ilu Akinmorin je okan, sugbon nipa idagbasoke ilu, ilu Akinmorin ni o rehin ju, nitorina nwon be Ijoba Ipinle Iwọ-Orun gidi lati ba won mojuto idagbasoke ilu na.

Awon egbe na si be awon Ijoye Akinmorin ki nwon mojuto ise ti Ijoba gbe le won lowo dada nipa owo-ori gbigba, ki nwon mase fi ise na se ojusaju pe, enikan je ibatan Bale tabi ibatan Otun-ilu tabi o je ogboju onisegun nitori owo-ori ni Ijoba ngna si olukuluku ilu. Ki awon adajo paapa mase fi ise won se ojusaju. Eyi ti onikaluku ba se ni a o ka, Bale Abinde la oju ona moto wọ ilu, o si ko kotu Ibile, ki Olorun fi orun ke e. Bena ni Bale Odeniyi se iwon iba ti o le se, ki Olorun fi orun ke e bakanna, nitorina ki olukuluku sa ipa tire ki a le ri ohun wi.

Nisisiyi, aye wa fun onikaluku lati so edun okan re fun Ijoba, aiye ti kuro ni aiye Captain Ross. Ajele pataki, baba Ogundele, ti o je pe Ijoba re nigbana, Ijoba "ari-igbodo wi" ni, aiye ti di aiye "tiwa ni Ijoba" o, nitorina abe Ijoba Ipinle Iwo-Orun ati Ijoba Ibile Oyo ki nwon ba wa ri si idagbasoke ilu wa Akinmorin o. Die ti aye wa fun ninu awon enia pataki-pataki ti o wa si ipade na ni awon Ogbeni N. O. Adegbola Ayanyemi, J. P. Akinrinola, James Akinyele, J. Alabi, S. O. Okedara (Akọwe-egbe); Mustafa Ajibi (Akapo-egbe); Latokun ati be e be e lo. Ajo'tu-egbe o.

IṢAKA, AWỌ-ARA TI KO LẸWA FẸRẸ BA AYỌ-ỌMỌGE RẸ JẸ

1. Peju gbosibo arin-ijo ti o ndun-yungya. Susie ko ri emi sunmọ o ba a je ina re si kuje, ti o ba se pe Joseph ti pe a pe ki o wa ba on jo ni!

2. Nigbati Prudence ore Susie ri i ki o saunkun, o mo ooi ibanuje ti o wa fun un. Ori paapa i ni arun obirewa iseka ara ri. O so asiri re fun Susie.

3. Susie bere imoran re, o si ko'ra o lere fun Mentholatum. Letan ojo meta o ri Prudence, o wipe "wo o! awo-ara mi ti jojo o si ndun mikiyi"

4. Nigbati nwon fun ni ere-Ije gbogbo enia ni o ngbe Susie jo ogelope Mentholatum ni o se nigbati Joseph di eniti o nba a je ti o ri ngbadun re.

Ooju, iseka tabi awo ti o bonije nile Mentholatum. Ba fi pa ara, o kanu a jojo, o ngbona dun o si nse iwosan, o nmu awo-ara jojo ati wonra, o ngbe awo-ara jojo ki o lemira si o si rewa.

Ri i daju pe Men-tho-lay-tum gan an ni o ra ti o wa nina aami ati ibi gegele fun awon. Mase ra awon adonipodi o.

Awon kanrinkan ti o dun e na ni

MENTHOLATUM CO. LTD
(Est. 1889), Slough, England

MENTHOLATUM

IPARA TI O DARA JU.

Ẹ ma a ka iwe

IROHIN YORUBA

nigbagbogbo fun irohin aladun

O NFUN NI NI ILERA

O NFUN NI NI AGBARA

Nje o ma wu o lati ni ilera ni? Aurọn ti ara won le ni inu won ona dun. O ye ki o ma mu "Phosferine Tonic Wine" lojojumo. Oti pupa patakl yi yio fun o ni okun, yio jeki o ma jeun dadara, iwo yio si ma sun wora. Mase jeki ẹnikẹni tabi irewesi ba o. Ma yo, ki ara si le! Ra igo "Phosferine Tonic Wine" si sohu onibara ne *l'ona aloni*. Egbogi atati ni.

PHOSFERINE TONIC WINE

agbo ti o gbadun . . .
mejetitun nla—yio se o ni ire.

Ma a fi igbadun ṣ'ayọ lori RUDGE

Keke Rudge ni awon okunrin olorire wonyi ngun. Keke Oyinbo Gesi ti o darajulo, o lagbara, o si se fokante, wa a ma a fi se gberaga ni ti o ba ni Rudge kan, yio wuko fun o dada l'opolopo. Ra Rudge kan nisisiyi—enikeni ni yio si ma a gbadun re ti nwon o ma a kan sara si e pe o mọ ohun ti o dara.

NI KẸKẸ OYINBO GẸSI T'ODARAJULỌ

RUDGE

Apalowo ṣe oku iya rẹ

AWỌ-EKITI.

NI ojo Ojobo ti ise ojo kejo osu kini odun yi ni Ogbeni Aminu Apalowo se nka iya re ti o ti ku ni ipari odun ti o koja yi. "Awo Rocky Mambo Orchestra Erewa" ni awon elere ti o se aisun ojo na moju. Ogbeni Francis Oyewole ko ere juju tire wa lati Iyin, Ogbeni James Folami si ko elere "kokoma" wa lati Eyio. Opolopo gbajumo lo wa lati Eko, Osogbo, Ilesa ati Ado-Ekiti fun eye oku na.

Omo oloku na nawo nara Inawo ati aseye ojo na bualya o le gongo, irohin ko to afojuba ni.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon alabaseye ojo na ni Ogbeni J. A. Ogunmola ati iyawo re, C. O. Ibatuyi ati iyawo re, Mustafa Aminu, Dada Ajibola, J. A. Onileowo ati Omidan A. Adeleye.

Ijọ Ṣọọṣi St. Michael Omupo ṣi Ile Ọlọrun titun

Ile Olorun Titun ti St. Michael Omupo

OMUPO.

NI ojo Aiku ti ise ojo kejidinlogun osu kejila odun ti o koja yi ni awon ijo Sooṣi St. Machael Omupo si Ile-Olorun titun ti nwon sese ko. Owo ti o pari Sooṣi titun na to ede-gbasan ponun (£17,000). Nigbati ojo sisi Sooṣi titun na ti ku ola ni awon ero alabaseye ti nwo wo ilu lati iba okere bi Eko, Offa, Ilorin, Oro ati Ajase-Ipo. Sooṣi titun na nikan ni o si ni ina lentiriki ninu ninu gbogbo sooṣi ti o wa ni agbegbe Ilorin.

Aseye isile ojo na bualya o le gongo. Alufa Ijo na ati gbogbo awon Ijo Sooṣi na fi orisirisi onje adidun ati oti orisirisi te gbogbo awon alabaseye ti o wa si ibi isile ojo na lorun. Ogbeni Reuben Adeoti ti aworan re wa ninu iwe yi ni akowe eto gbogbo aseye isile ojo na.

Ogbeni Reuben Adeoti, Akowe Eto Isile Sooṣi na

Eka Egbe Afenifere Omupo se i ade

Omupo.

NI ojo Abameta ti ise ojo kokanlelogbon osu kini odun yi ni awon Eka Egbe Afenifere (Action Group) Omupo se ipade. Awon ti o wa si ipade na to egbedogbon (5,000), awon ti o ba ipade na soro ni Kansilo R.A. Olaoti; Ogbeni A. B. Bakare, Malam Kadiri Abiola, Ogbeni Jacob Adeoti. Ajase-Ipo ati Malam Buraimo Biriyi Igbaja.

Ni ipari ipade na, awon omo Egbe Olomi (NPC) ti o wa wo Egbe Afenifere (Action Group) to igba (200) enia, Ijoko Ipade na si gbadura fun Oloye Obafemi Awolowo, Alakaso Ijoba Ipinle Iwo-Orun pe, ki Olorun jeki o bori awon ota re ninu idibo wole Igbimo Apapo Ijoba Naijiria ti o mbo yi. Nwon si pari ipade na pelu adura.

Ayanda gbe Ayanroke ni iyawo

IJABE LEBA OYAN.

NI ojo Abameta ti ise ojo kokanlelogbon osu kini odun yi ni Ogbeni Amos Olayaju Ayanda gbe Ayanroke Adelokun Abeo ni iyawo alarinrin, oko iyawo ati awon ebi re nawo pupo, Egbe Afenifere si se gudugudu meje ni ibi igbeyawo na. Ali ile Esa ati Abidoye ati Abioye Osogbo ti kokoro ilu won ati sekere dabira ni ojo na.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon alabaseye ojo na ni awon Ogbeni Oba Gabriel Afolabi, Samuel Eniola, Emmanuel Bangbade, Samuel Ode, S. Oladeji, Lawani Odofin ati Gbadamosi Omoniyi.

Ki Olorun fi ibunkun si igbeyawo na ki O si fi ire kari gbogbo awon alabaseye ojo na.

Olaoti komojade

OMUPO.

NI ojo Ru ti ise ojo keje osu kini odun yi ni Kansilo Olaoti se ikomo omobirin ti Olorun fi ta on ati iyawo re lore. Katikisi Kunle Aderogba ni o se eto isin isomoloruko na. Nwon si so o ni Mosunmola Oluwayemisi, awon obi omo na si fi jife ati mimu te gbogbo awon alabaseye ikomo na lorun. Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon alabaseye ikomo ojo na ni awon Egbe Omo-Ogun Igbala, Egbe Ifelodun; Egbe Iwa-mimo Egbe Olorun wa pelu wa ati Egbe Alanu ti ise egbe iya omo na.

Ki Oluwa da omo na si.

Egbe "Ibokun National Association" sere ajodun kini

IBOKUN.

NI ojo Ru ti ise ojo kerinlelogun osu kejila odun ti o koja yi ni awon omo Egbe "Ibokun National Association" sere ajodun kini lati sami si ipari odun 1958 ati bere odun 1959. Nwon se ipade gbogbo egbe na ni ojo na, nwon si saiun mojumo ojo keji ti ise ojo Odun Keresimesi. Ogbeni Kundayo Kolawole Alamojuto Ise agbegbe Ijesha ni o se Alaga ipade na, okunrin eleko-ijinle kan, Dokita F. A. Ajayi si fun awon omo Egbe na ni irohin didun nipa" ilu Oyinbo ti o ti lo ko eko fun odun mesan abo.

Ni ogbonjo osu na, nwon jo ijo alarinrin yipo ilu ka-kiri ni agale ojo na, nwon jo ijo gidigbo ninu Obongan Apejo nla ilu won. Nigbati o di ojo karun osu kini odun yi ni nwon lo fi ere bolu-afesegba pari ere ariya ajodun na ni ori koriko Ile-Iwe St. Peter Ibokun. Awon Oloye Egbe ti nwon yan fun odun 1959 yi ni awon Ogbeni J. O. Bolaji, Baba Egbe, Laiye Kolawole, Ghakeji Baba Egbe, Iyaafin Larewaju Awogboro, Iya-egbe; awon Ogbeni Deniyi Fakolujo, Alaga; Deji Fadavini, Akowe; Jine Ogunni, Akapo; Deji Odaniyi, Balogun; Owolabi Akowe-Owo ati Rufus Adeitan, Akowe Isede.

Ki Oluwa se odun na ni odun ayo fun gbogbo wa. Amin.

Ayọka jalaisi

IWO.

NI ojo Ojobo ti ise ojo karun osu odun yi ni Ejiyooye Ayoka ku si Agboile Awara Osinjobi ni Oke Adan, Iwo. Gbara ti o ti ku ni ese awon omo-oloku na, awon bi Tijani Akanmu, Ashafa Akanbi, Latundun Saka, Sabitiyu Aiyeniyina, Adediran Ayoola, Salawu Alamu, Bilawu Saka, Ashiawu Iyinola, Anike ati Adewuyi Ibadan ti pe si ibi oku na pelu awon ebi ati ore. Lesekese ni nwon si ti se eto ti nwon si sin in ni irole ojo na gan an.

Bilawu Aremu ti Ile Mogbokun Gidigbo, Iwo ati gbogbo awon omo-oloku na nawo nara, nwon fi jije ati mimu te gbogbo awon alabaseye isinku na lorun.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon alabaseye ojo na ni awon Ogbeni Moriamo Amoo, Adu Adigun, Ladepo Awokekere Lamidi Ikanmu, Ganiyu Ajani ati Raufu Olode.

Ki Oluwa jeki ehin oku o dara.

Warakaṣi Kraft ngmu onje dara pẹlu iyanu

Fi je buredi tabi akara, Oyinbo wo.

Enikeni ni o gbadun Warakaṣi Kraft. O gbadun pupo lenu, o si dara fun gbogbo awon ebi re paapa fun awon omode. Iseju kan pere ni wa fi se eto warakaṣi omo buredi tabi akara Oyinbo ti yio si fi di onje. O je onje imarale. Bere Warakaṣi Kraft ni soobu ti o ti nraja. Wa a si ri i ni gbefe ninu agolo alawo bulun tabi pupa resi-resu.

KRAFT

KRAFT FOODS LIMITED, MORRIS HOUSE, BERKELEY SQUARE, LONDON, W.1

Alakowaba-ole ti i ko ba ero-ọ na

Lati ọwọ " Awofẹẹrẹbonu ", Minna

INU mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati fi itan kekere yi derin pa awon ojogbon onkawe "Irohin Yoruba" elegbe mi. Itan na mu ogbon dani o si ko wa wipe bi enia ba pe ni fun iranlowo, o to ki a fi lakaye wa iru iranlowo na ki a to o se e fun un ki inu rere ma ba a ko ori buruku ba ni. Itan na le bayi:—

Ni igba laitaf, okunrin kan wa tee ole fija si o nse. Nigbati o fe lo ji isu wa ninu oko-oloko ni ejo kan, o mu apere meji, osuka meji ati ada meji dani, bi o ti de oko na, o wa isu kun inu apere mejeji, o fi osuka kookan le awon apere na lori, o si tun fi ada kookan le awon apere na lori pelu.

Nigbati o ti se bayi tan, o lo duro leba ona lati pe ero ona kan ti o ba nrekoja pe ki wa gbe ru on, ko pe pupo ti o ti nduro ti o fi ri okunrin kan ti o nto ona na koja lo, bi o ti rin de odo okunrin yi ni awon mejeji ba ki ara won, okunrin ti o ti nduro na si be e pe ki jowo tele on kalo si inu oko ki o gbe ru on.

Nigbati nwon d inu oko na, eniti o fe gbe ru u ri apere isu meji pelu ada kookan ati osuka kookan lori won, sugbon ko wi kinikan si i, o ni ki o bere ki on gbe ru u, bi o si ti fe gbe ru u ni oloko ba yo si won lojiji, o ni eeyin faniyen? Sugbon okunrin ti o nfe gbe ru u si so pe, on ko mo nkankan, o pe on lati wa gbe ru on ni, enikeji si so pe, iro ni o pa, awon mejeji jijo wa ji isu wa ni, o ni isoro ni ki on nikan mu apere meji, ada meji ati osu ka meji wa fi ji isu wa ninu oko,. Oloko ti nwon rojo fun na si so pe, iyen ko seese, nigbana ni oloko ba ko won lo si iwaju Oba.

Nigbati oloko na ko awon okunrin mejeji na de iwaju Oba, o rojo pe, awon okunrin mejeji na wa ji isu wa mo ibe ni on ba fi mu won ninu oko on ni, on ka won lole wa si iwaju Oba. Nigbati nwon bere ejo lowo ole ti o so ji isu wa, o ni awon mejeji ni awon jijo lo i isu na wa. Nigbati nwon bere ejo lowo okunrin keji, pelu omi-aju ni o fi nrojo fun Oba pe, jeje on ni on nrekoja lo ni oju ona ti on si ba okunrin (ajisuwa) yi leba ona ti o be on pe ki on jowo kalo gbe ru on ninu oko.

O ni bi on si ti de ibe lati gbe ru u ni oloko ba de ti o si mu awon mejeji lole. sugbon lotito, on ba apere isu meji ati osuka kan ati ada kan lori okookan eru isu na, on ko si mo bi o ti je. Pelu ekun ti o nsun ati ejo ti o nro, ko si eleri fun oro re. Oba ko si le gba a gbo, nitorina o pinnu lati je idajo ijiya fun awon ole mejeji na.

Nigbana ni anu wa se ole ajisuwa yi nitori ekun ti ekeji re nsun, o si jewo fun Oba pe, ki o jowo mase je ekeji on ni iya nitoripe ki ise ole otito si ni gbogbo oro re ti o so niwaju Oba. Sugbon on paapa ni alakowaba-ole, on ko ba a ni Ko-mowo ko-mese nipa oran na, Oba si se idajo fun ole ajisuwa na, o si da ekeji re sile pe ki o ma a lo ni alafia.

Lowo akoba ati adaba. Oluwa rere gba wa o.

Olotu mo dupe aye ti e gba mi.

Idahun Alfa Bọlaji Akewukewe

(Lati oju ewe karun)

taki ti o doju ti iro Akande ti o so pe Annabi gba iyawo Zaidu ni Surat 33 ayat 37 ti o so pe Zeidu ati Zeina ti ko ra won sile nwon si ti pinnu ji yigi won funra ra won ni ife- inu ara won, ki si nse eewo ninu Alukuriani lati fe obirin ti o ko oko tabi ti oko ko sile (Surat 2 ayat 230) Bibeli paapa yonda (kosile (Deut. 24 ese 1-2), tun wo Jeremiah 3 ese 1.

Akande so pe Annabi pa iro laisi eri oro kan ninu Alukuriani ti o ja Annabi ni koro oro kankan lati oke de ile. Akande mu awa Musulumi ranti oro ti ki nse otito ti Jesu so ni Johannu 13 ese 34 pe "ofin titun kan ni on Jesu fi fun nyin pe, "ki e feran omonikeji nyin". Mose ko ha ti so ni Liffittiku 19 ese 18 pe "ki a fe omonikeji wa bi"?

Bawo ni ife omo nikeji ti o ti wa ninu ofin Mose ju edegbeta odun lo ki Jesu to de se le je ofin titun ti Jesu mu wa? Nigbati ki nse odo Jesu li a ti koko gbo o, emi aisoto ko le jeki Akande ti ipa eyi jewo pe Jesu puro lati je ofin ojo pipe ni titun. Oro ti awa Musulumi je ogede eri otito. Sugbon iro pipa ti ko ba eri ti Akande njuwe mu sa a ni awon oro Akande, enia ti ki nba gbo oro totun tosi je sina jina bi Akande nipa iro Akande. A dupe lodo Olorun Oba Ododo ti o so ninu Alukuriani Surat 33 aya 38 pe ebi ese kan ko si fun Annabi nibi ese ti Akande nfi iro pipa ra mo Annabi lorun. Olorun tile so ninu Alukuriani Surat 93 ayat 3 pe On ko ko Annabi on ko si korira re. Eyi yato si ti Jesu ti o mo pe Olorun ko on (Mattu 27 ese 46).

(KOI TI PARI)

E ma a ka Iwe

IROHIN YORUBA

nigbagbogbo a fun irohin aladun

Egbẹ'birin Ekiti f'ọkan tan Oloye Awolọwọ

Aworan yi ni ti awọn Egbẹ'birin Afẹnifẹre Ekiti ti a so irohin ipade won ni oju ewe kini iwe wa ose ti o koja pe nwon ni igbekele 'nu Oloye Obafemi Awolowo Olori Egbẹ Afẹnifere ati Alakoso Ijoba Ipinle Iwọ-Orun.

Awọn Enia Jankanjankan Gba wipe - - -

KO si wipe a sese nse ojopa-inu ki a to mo pe oti Star lokiki pupo! to fi je pe agbara ati oorun didun inu re ni ohun to fani mora. Gbogbo oro wonyi fihan pe oti Star je oti ti o da seki, o si nteni lorun.

STAR

ni ọti ti o darajulọ

NI TIRẸ

ESAN KOGB'OGUN

(Lati oju ewe kẹrin)

olupọnju, tabi ẹniti o ba ri pe o ti dagba, darugbo, ti ko si oluranlọwọ kan fun un, iru sara bẹ ẹ ni o je iye fun adura, nitori, iwọ Erukobodo mọ daju pe, bi ko ba si Iye lara Eiye ko ni le fo, nitorina, gbogbo eda ti o ba nfi sara anu kun adura re were-were ni adura e yio gba, nitori Olorun funra ara Re ni o ti so eyi ni asotele wipe: Enikẹni ti o ba di eti re si igbe oluponju on tikala ara re yio ke pelu, sugbon A ki yio gbo. Eniti o ba fi ninu ohun ini re fun olupọnju oluware ki yio se alaini. Owe ori 21 ese 13 ati ori 28 ese 27.

DURO DE ASIKO TI OLUWA

Ninu alaye ti mo nfi ta o lore yi, emi Ore Asekupani tun fe fi ye o wipe, opolopo ni eda ti o mbe ni ile aiye, ti nwon nse adura ti nwon ki i si ni suru di aseko ti Oluwa, nwon a ma a rti abo adura won kiakia, nwon a ti gbagbe iwa odale, iwa modaru ati iwa ijamba ti nwon ti hu koja sehin, beni, adura sise si Olorun o nfe opolopo suru, gegebi o ti mo daju pe, ko si eniti o le fi ikanju la obe ti o gbona ki obe na ko wo inu pelu irorun.

Gegebi apejuwe, oro na dabi ki o ni omo kan l'odo, ki omo na je oniwa rere tabi olotito omo, ki omo na toro ohun kan lowo re, nje o le fi ohun na fale ki o to fun un? Sugbon, bi omo na ba je janduku omo, tabi omo ti ko gba ikilo iwo baba re, bi omo be ba toro ohun kan lodo re, nje o ko ni ronu jinle ki o to le fun un ni ohun ti o nfe? Eyi ni mo le fi se apejuwe fun gbogbo eda ti nwon ki ife pa ofin Olorun mo, ti nwon nse adura, ti nwon tun nkanju wipe adura won ko tete gba gba.

PE OLUWA NI ORUKO RE

Ohun ti Emi Ore Asekupani yio tun fi ye iwo ore mi Erukobodo ni wipe, bi o ba to asiko fun o lati s'adura si Olorun Eleda re, mo fe ki o ma a fi tokantokan ke pe E, ni oruko Re, mase da oruko miran po mo oruko Re. Gegebi apejuwe:—Eyi dabi pe, ki o lo sibi ariya ere kan, ki onilu ti o nlu ilu fun nyin ki o ko oju ilu si o lati ki o, ki onilu na bere si i fi oruko tabi oriki Alafin tabi Eleko ki o, nigbati iran re ko ba Alafin tabi ti Eleko tan, ore mi! nje ori re o le wu debiti iwo yio fun onilu na l'owo?

Bi o ba fun onilu na lowo, emi ri i wipe o fi se oju alye ni, ki ise wipe o fun un pelu idunnu, beni ohun ti a ko ba finu-findo fun enia, nko lero wipe inkan na, o le se eniti a funni anfani, mo fe ki iwo Erukobodo mo daju wipe, eyi je ohun pataki ti ki ije adura o gba lasiko bi o ba to asiko fun o lati ke pe Oluwa Olorun re, mase jeki ero miran tun wa lokan re ju adua ti o ba nfe lo.

"Eleti gbaroye" ni Oba Olodumare, iwo ore mi Erukobodo si mo daju wipe, Abiyamo ni Olorun. On ni ki igbo igbe omo Re ki o mase ta eti, were, bi o ba fi okan kan ke pe Eleda re, kosi ohun ti iwo yio bere lowo Re ti ko ni re o lekun. Ore Erukobodo iwonba ohun ti emi Ore Asekupani yio fi ta o lore niyi, bi o ba tele alaye mi, yio dara fun o laiye, yio si tun dara fun o l'ajule orun pelu.

Ki nto dagbere fun o, o to ki nfi adura yi ranse si agbaiye:—Oluwa, ranti gbogbo Onigbagbo Ododo ti nwon mbe ninu iponju ati idewo Re ninu aiye ati gbogbo awon ti nwon fe anu ati iranlowo Re, mu asako pada bo sile, fi ilera fun gbogbo awon ti mbe lori akete aisan ati ireti fun awon ti nwon nku lo Oluwa, anu Re dara pupo awon eda Re yio gbekele abe iboju Iye Re. Iwo ni eniti ise ilana agbara, ma sai jeki awon ti O fi se agiwaju nlie aiye ni iwa rere ati iberu Re, fi ogbon orun kun awon Ijoye ninu, mase jeki awon ti o fi se Oba nile aiye lodi si otito Re, bikose ohun ti yio ma a gbe ogo Re ga, to awon Onidajo si ona lati se idajo ododo, masai jeki igi oko so eso rere, ki O jeki awako gunle si ebute alafia, fi ibukun Re fun onise owo, ki onisowo ma a jere kun ere, ki ayipada buburu jina si onise oba, jeki aboyun bi tibi-ti're, so agan di olomo, fi oju rere wo gbogbo awon ti nwon nse ise rere fun idagba soke Ijo Re, se bi mo ti nfe yi fun won, fun ogo oruko Re. Ase, beni ki o ri. O digba o, ore mi owon.

Enyin onkawe, bi Irohin mi l'ona "Ilu Arikogbon orun awon Elese" ti mo niyi. Emi Erukobodo dupe dupe lowo t'omode t'agba nyin fun opolopo suru ti e ti nfi ka irohin na lati ojo ti mo ti bere re titi debi ti mo pari re si yi, emi rii daju pe Irohin yi yio je okan ninu awon ohun ti a nri fi kogbon ninu Iwe "Irohin Yoruba" yi ati wipe, inu yio dun bi a ba le fi Irohin ti "Ore Asekupani" yi kogbon, nitoripe, awon baba nla wa, nwon a ma a pa a lowe wipe:—"A fi ogbon ologbon se ogbon ki npe agbalagba ni were". Toto o, o sebi owe o.

Gegebi emi Erukobodo ti se so ninu Ibere Irohin ajo mi lona "Ilu Arikogbon yi wipe, bi Eleda ba da emi mi si, nko ni salai ko fi aworan gbogbo ohun iriri ti mo ri ninu irin-ajo mi na ati aworan temi paapa han agbaiye ninu iwe kika miran, eyiti mo fe ki o je ohun iranti aiye ralye fun awon aromodomo ati awon ti mbo lehin, bi mo ti wi na ni ngo se lagbara Olodumare, ki Olorun ko da emi gbogbo wa si ki ajinde ara ko si ma a je fun Olotu Iwe Irohin yi. E f'oju s'ona.

Olotu, iwo ni emi a ba ki, iwo ni emi a ba yin fun opolopo aye ti e gba mi ninu Iwe "Irohin Yaruba" ti ise akomo logbon yi, adura atokanwa mi si o ati si gbogbo awon olubaise po re ni wipe, ki Oluwa ki o fi ibukun akunwosile sinu ile ohun ona nyin. Mo dupe o.

Enyin onkawe, abo mi fe e o, o digba kan na o.

Nibiti edaran kan gbe nyo ayo amoribo ninu ejo kan ni ologo tun ra a mu

ILESHA.

NI ojo Isegun ti ise ojo ketadinlogun osu yi ni awon olopa Ijoba Ibile Ilesha re okunrin kan mu ti oruko re nje Joseph Ogunlusi ti nwon tun npe anije re ni 'Okere—Ajenje' larin agbo-ijo nigbati o njo lowo fun ayo pe. Adajo da a sile pe ki o ma a lo ni alafia lori esun kanna ni ologo tun ra a mu fun; nitoripe esun ti nwon ba a sejo fun yato si ese ti o se ni nwon se da a sile ni akoko ki ologo to tun mu u.

Iyabo Thomas, eniti ose akowe-Iriju fun Publicity Officer ni Nigeria House, ni Ilu Londonu, igbagbogbo ni awon enia ma a ngbadun re ti nwon si i nisa ye a si fun awo-ara re ti o jelo ti o si ndan. Alaye ti i ma a se fun awon ti o ngbadun ewa re na ni wipe "Ose Atawose Lux Toilet Soap ni on nlo nigbagbogbo".

Ti o ba nlo ose atawose Lux fun iboju, ki ise pe o to je lasan ni, o nse eogun—atewase funra re si pelu.

Ti ifofo ose atawose Lux ti o kunna mulo-mulo la wa ni oja ati orun re—wa a moo lara gegebi ori-amo lesekese. Fi sibe fun igba kinun nigbana ki o wa fi omi nan gbogbo ifofo ose na kuro, ri i pe o san an mo ki o wa fi ase-inura nu oju re ki o gbe.

Lesekese awo-ara re yio beresi mo iyato—yio si tubo ma a dan si i yio si tutu. Abaje ti awon arewa obirin Naijiria fi nlo ose atawose "LUX TOILET SOAP".

Enyin paapa le tubo rewa si i ti e ba nlo ose atawose "LUX TOILET SOAP"

Awọn Apapọ Ajọ Babalawo fẹ ṣe ipade l'Eko

AWON apapo gbogbo Ajọ babalawo yio ṣe ipade won ti nwon ma a nse losu meta-meta. L'Eko ni nwon yio ti ṣe e, ni ile Oloye Adesina Awotunde Ajanaku, Araba Eko • ni 55 Okepopo Street, I'Eko. ni ojo Abameta ti ise ojo keje osu keta odun yi ati ni ojo kejo osu kanna.

Awon Iko ajọ babalawo yio ti origun mererin ile Naijiria ati ti ile Faranse wa si ipade na, awon eka ajo na ti ilu Eko bere si se ipalemo lati ma a gba won lalejo lati ojo kefa osu ti nwon yio se ipade na.

Musitafa Amọtoto gbe Rafatu niyawo alarinrin

Guni Station leba Minna.

LAIPE yi ni Ogbeni Musitafa Amototo gbe Rafatu niyawo lona eain Musulumi. Oko iyawo na nawo pupo lojo na. O fi onje ati oti te gbogbo awon alabaseye ojo na lorun. Irohin ko to afojuba ni aseye ojo na je.

Die ninu awon ti o wa sibi aseye ojo na ni awon Ogbeni Lawani Erinfolami, M. B. Adebayo, A. B. Oladipo, M. S. Olarinoye, Amusa, Okoh, Awomosu, Adebote, Muniru, Job Oiude ati S. B. Bolarinwa.

Ehin iyawo ko ni mọ eni o.

ṣugbọn

TISANE de DURBON

nṣe dada nigbagbogbo ni!

Da awon inu-riran, esanri ati iyonu edo wonnni duro! mu TISANE DE DURBON lojojumo. Ko ni si alrigbeya fun e mo! Ko ni si iaaka ara mo! Awon irora lakuregbe re yio lo. Jeki alafia ati idunnu je opin obun ti o nlebo. TISANE DE DURBON nse dada nigbagbogbo ni. Atejese iyano ni. Ra a ninu apoti pupa ti o ndan yinrin-yinrin.

Awọn ti o nṣe e ni
LABORATORIES J. BERTHIER, Grenoble,France
MA A MU U FUN ALAFIA RE NI OJOJUMO

Onisowo ase ti ise re ngberu nfi owo re pamo si

BARCLAYS BANK D.C.O.

Ki iwọ na bereṣi fi owo re pamọ sibẹ loni

Ilana eto Iwe Orire idije bọlu afẹsẹgba ilu oyinbo

ILANA ETO AWON OMI TI KO NI ETO AFOJUDA

OPOLOPO awon enia ti o feran idije orire wa ti nwon ko si feran lati ma a lo eto afojuda.

Fun iru awon be e, mo le so ni gbolohun kan pe, awon ila kookan ti dara to. Iba ohun ti o nfe ni pe ki o fi akoko die ati ibarale ko ise idije orire.

Ilana eto awon omi ti ose yi, ti ki ise afojuda rara, sugbon ti a to ni merinla oni ila kookan, gegebi eyikeyi ninu afojuda gan an ni odara, nitoripe, bi marun ninu omi mesan ti a yan ba dogba, ni kukuru, wa a ni ireti fun ipin kan, boya o le je merin tabi mewa.

Ko si mu wahala dani rara lati ri i pe ona pupo wa ti a le fi ye ipin orire pelu omi meta pere ti o dogba.

Ijọba ti yẹgi fun Nwiboko Obodo

ENUGU.

NI ojo Isegun ti ise ojo kerinlelogun osu ti o koja yi ni Ijoba yegi fun okunrin apania Nwiboko Obodo ti aworan re wa ninu iwe yi ninu ogba ewon Ijoba ni Enugu ati awon merin ti nwon jijo gba idajo iku.

Ni odun ti o koja yi ni okunrin na ti gba idajo iku ni Kotu Ganran Abakaliki pelu awon merin miran—Nwegete Ogbo, Mbeke Awam, Nwugbana Nwankwo ati Nwaboyi Mgbator fun pipa ti o pa iyawo re Nwangbo Igboafi. Nse ni nwon fi okun so Oloye Obodo na lorun ro soke titi ti o fi ku ati awon elegbe re merin yoku pelu.

"Obodo ti nwon yegi mọ lese yi ni Oloye Ishieke ni Ekun Abakaliki—on ni o da egbe imule kan ti nwon npe ni "Odozi Obodo Secret Society" sile, egbe yi si ti fi opolopo odun da eru-jeje sile larin opolopo adugbo ninu Ekun Abakaliki. Titi di ipari osu kini odun ti o koja yi igba o din mejo (192) ejo apania ni nwon se ni agbegbe Ogoja, enia metadinladota ni nwon ju sewon, enia mokanlelogoji ni o mori bo.

Awọn ọlọpa mba aboyun kan ṣẹjọ ajọmọgbe.

SAPELE.

NI ojo Isegun ti ise ojo kerinlelogun osu ti o koja yi ni Adajo Kotu Kekere Kini ni Sapele taari ejo obirin aboyun kan Lucy Oriohonusa Edu, eni odun medogbon si Kotu Ganran fun esun ti awon olopa fi sun pe, o ji omo osu meji gbe. Opolopo awon abileko obirin ti oro na je iyanu fun ni o pe soso si Kotu lati le ri oju odaran na.

Ejo ti awon olopa ro ni pe, odaran na ji omo titun na gbe mọ omodebirin ti iya re fi so lowo, o si tun gbe omo na lọ ju sile nile obirin miran ati ibe ni nwon ti gbe omo titun na wa fun awon olopa.

ALL-IN-A-LINE GUIDE

FORM AND FORECASTS FOR SATURDAY 7th MARCH 1959

Fore-cast	FOOTBALL LEAGUE			
	DIVISION 1			
2—1	Aston V v Leeds Utd	50	22	28
X—2	Blackburn v Burnley	49	22	29
X—1	Blackpool v Bolton	53	23	24
2—1	Chelsea v Luton	56	23	31
X—2	Man Utd v Everton	56	20	24
2	Newcastle v Preston	42	21	37
1	Notim F v Birmingham	56	22	22
1	Portamouth v Man City	61	19	20
1	Tottenham v Leicester	63	18	19
2	West Ham v West Brom	39	22	39
1	Wolverhampton v Arsenal	61	19	20
	DIVISION II			
X—2	Barnsley v Bristol R	48	22	30
X—1	Brighton v Scunthorpe	54	22	24
1	Bristol C v Stoke City	55	22	23
1	Cardiff v Swansea	58	21	21
1	Charlton v Sunderland	62	18	20
2—1	Grimsby v Sheffield Wed	51	20	29
X—1	Huddersfield v Ipswich	50	23	27
1	Liverpool v Fulham	56	21	23
1	Middlesbro' v Lincoln C	69	18	13
X—1	Rotherham v Derby C	49	24	27
1	Sheff Utd v Leyton O	62	19	19
	DIVISION III			
1	Bournemouth v Wrexham	63	23	17
1	Bury v Halifax	61	19	20
2—1	Colchester v Bradford C	46	22	32
1	Doncaster v Notts C	57	21	22
X—2	Norwich C v Southampton	51	21	28
1	Plymouth v Mansfield T	59	19	22
X—1	Q P Rangers v Newport C	57	21	22
X—1	Reading v Hull City	51	23	26
X—2	Rochdale v Chesterfield	46	24	30
X—1	Southend v Accrington	50	23	27
X—1	Stockport v Brentford	46	25	29
X—1	Tranmere v Swinton T	51	23	26
	DIVISION IV			
X—1	Bradford v Carlisle	56	21	23
2—1	Chester v Gateshead	51	21	28
2	Crewe v Shrewsbury	42	23	35
1	Crystal P v Oldham Ath	59	20	21
2	Hartlepools v Millwall	44	22	34
X—2	Northampton v Coventry	49	22	29
1	Port Vale v Barrow	59	20	21
2	Southport v Walsall	37	24	39
X—2	Torquay v Darlington	49	22	29
X—2	Watford v Aldershot	50	21	29
X—1	Workington v Exeter	55	20	25
1	York City v Gillingham	60	21	19
	SCOTTISH LEAGUE			
	DIVISION I			
X—1	Aberdeen v St Mirren	55	20	25
2—1	Airdrie v Patick	49	20	31
1	Celtic v Dunfermline	58	19	23
1	Hearts v Q of South	81	13	
X—1	Kilmarnock v Falkirk	56	21	23
2	Raith v Motherwell	39	22	39
1	Rangers v Clyde	62	19	18
X—1	Stirling A v Dundee	55	22	23
2	Third Lanark v Hibernian	42	23	35
	DIVISION II			
1	Brechin v Alloa Ath	52	19	29
1	Cowdenbeath v Stranraer	67	18	15
2—1	Dumbarton v Arbroath	51	20	29
2	Dundee Utd v Ayr Utd	29	20	51
2—1	E Stirling v Albion R	52	21	27
X—2	Forfar v Queen's Park	52	21	27
1	Hamilton v Berwick	67	18	15
1	Morton v St Johnstone	47	22	31
1	Stenhousemuir v Montrose	64	18	18

X	—	X	—	X	—	X	X	—	—	—
—	X	—	X	—	—	—	—	—	—	—
X	—	X	—	—	—	—	—	X	X	X
—	X	—	—	—	S	—	—	—	—	—
X	—	—	—	X	—	X	—	X	X	—
—	X	—	—	X	—	—	—	—	—	X
—	—	X	—	—	X	—	X	X	—	—
—	—	—	X	—	X	—	—	—	—	—
—	—	—	—	X	—	—	XX	—	X	X
3d	3d	3d	3d	3d	3d	3d	3d	3d	3d	3d

PICK OF SELECTIONS IN ORDER OF MERIT

Homes: Middlesbrough, Rangers, Tottenham, Bournemouth, Charlton, Sheff Utd., Portsmouth, Wolves, York.

Draws and Treble Chance: Stockport, Rochdale, Rotherham, Reading, Hudderafield, Blackpool, Southend, Tranmere, Stirling.

Aways: Walsall, West Bromwich, Preston, Shrewsbury, Millwall.

—ARTHUR JAMES

EYI NI ỌJỌ AWỌN ỌJA ILẸ WA.

ỌJỌ AJE 2ND MARCH (MONDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko ati Agbegbe re Abeokuta.	Obun Eko, Ojo.
Ibadan.	Atan, Agbado, Ifo, Itoku, Kobape Isaso, Odeda, Ibara, Mowe.
Ijebu.	Ijaiye-Orile, Iressi, Obada, Egbeda, Oyedeji.
Ijesha.	Ilishan Odogbolu, Atan Imope, Ishan, Isara, Imodi, Akesan.
Ondo ati Eti Odo.	Ilase, Epe, Iloba, Iperindo Imuroko, Erinmo, Esa-Oke Lodẹ-Idoka, Otan.
Egbado.	Agirifon-Iiutitun, Odolomu, Igbotako
Ogbomoshọ	Aiyetoro, Tata Randu Ado-Odo Iressa-Du, Arolu, Egbeda, Jabata, Oke Imale.
Ekiti.	Egosi, Odo-Aiyedun-Okemesi.
Ibinni.	Kokori.

ỌJỌ ISẸGUN 3RD MARCH (TUESDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko a Agbegbe re Abeokuta.	Mushin, Badagry. Otta Abalabi Ṣodẹkẹ, Owode.
Ibadan.	Omida, Ilawo, Owowo, Obafemi.
Ijebu.	Oja-Oje, Ogburo. Ikenne, Okunowa, Erunwon. Ijebu-Ijesha, Omu, Ago-Iwoye Mojoda.
Ijesha.	Osu, Itagu, Idoko, Iloko, Odogbo Owode, Idoka, Ilare.
Ondo ati Eti Odo.	Ishrua, Aye, Erinketa, Agbabu. Igbogi, Arowona Idofin.
Egbado.	Ilobi Igbogila, Ijoun, Imasa.
Ogbomoshọ	Araromi, Iregba
Ekiti.	Erẹkẹsan.
Ibinni.	
Delta.	
Igbajo.	Iloro

ỌJỌ 'RU 4TH MARCH (WEDNESDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko ati Agbegbe re Abeokuta.	Agege, Ikeja. Lafenwa, Obada, Obae, Kajola Ajegunle, Idogo, Ogunmaki Itori
Ibadan.	Lalupon, Ibuko.
Ijebu.	Isara, Ita-Aganda, Ibefun Ipara. Imodi, Atikori, Imushin, Mamu
Ijesha.	Esa Oke, Iwara, Ejioro Odo, Ibokun, Esa Odo, Ibala.
Ondo ati Eti Odo.	Igbo-Egunren.
Egbado.	Idi-Omi, Lasilọ, Igan Okoto, Atta
Ogbomoshọ	Oko
Ekiti.	Ifaki.
Ibinni.	Uromi.
Delta.	

ỌJỌ 'BỌ 5TH MARCH (THURSDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko ati Agbegbe re Abeokuta.	Oyingbo, Ejirin Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi, Sodẹkẹ.
Ibadan.	Ogunjana, Lagun, Sagbe, Olode
Ijebu.	Aiyepe, Sagamu, Ita-Osu, Ogere Iroiu, Itele, Ita-Oloti, Agbowa
Ijesha.	Imodi, Oru-Awa Ibodi, Bode, Kajola, Oluwa'da, Erẹkẹta, Imesi Ile.
Ondo ati Eti Odo.	Oka, Ilara, Abigi, Aiyetoro, Epe.
Egbado.	Alagba, Ilaro, Sunwa, Iboro.
Ogbomoshọ	Obada Gambari.
Ekiti.	Ilogbo, Oke-Aiyedun, Idogun, Ishan
Ibinni.	Eke.

ỌJỌ ETI 6TH MARCH (FRIDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko ati Agbegbe re Abeokuta.	Obun Eko Ikosi (Epe) Atan, Agbado, Ifo, Itoku, Isabo Odeda, Ibara, Itori, Oja-Iro.
Ibadan.	Ijaiye-Orile Iressi, Obada, Egbeda, Oyedeji.
Ijebu.	Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Ishan, Isara, Imodi Ikosi
Ijesha.	Esa-Oke, Ilase, Epe, Iloba Iperindo, Imuroko, Erinmo, Otan Ipetu, Ita Apa. Odojomo, Igbotako, Ileoluji
Ondo ati Eti Odo.	Obunkekere, Agirifon-Iiutitun
Egbado.	Aiyetoro, Tata, Randu, Ado-Odo
Ogbomoshọ	Iressa-Du, Arolu Egbeda
Ekiti.	Egosi, Odo-Aiyedun, Okemesi
Delta.	Kokori.

ỌJỌ ABAMẸTA 7TH MARCH (SATURDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko ati Agbegbe re Abeokuta.	Mushin, Owode, Otta, Abalabi, Sodẹkẹ. Omida, Ilawo, Owowo, Obafemi Mokoloki, Orile-Imo, Geleodun
Ibadan.	Oja-Oje, Ogburo.
Ijebu.	Ikenne Okun-Owa, Eruwon Ijebu-Ijesha, Omu, Ago-Iwoye Mojoda.
Ijesha.	Osu, Itagun, Odogbo, Iloko, Ipetu, Owode, Idobo, Idoka Ilare, Ijeda, Eti Oni.
Ondo ati Eti Odo.	Agbabu, Igbogi, Ishua, Erinketa Arowona, Idofin
Egbado.	Olorunda, Kajola, Ilobi, Eredo.
Ogbomoshọ	Araromi, Iregba.
Ekiti.	Erẹkẹsan.
Igbajo.	Osele.
Ibinni.	Iloro.

ỌJỌ AIKU 8TH MARCH (SUNDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko ati Agbegbe re Abeokuta.	Agege, Ikeja, Ebute Ero, Ajido. Lafenwa, Obada, Oba Kajola Ajegunle, Idogo, Ogunmaki Itori, Omu-Ajoyinre, Obanisunwa, Ajura.
Ibadan.	Ibuko, Ialupon.
Ijebu.	Ibefun, Atikori, Imushin, Isara, Imodi, Ipara, Mamu.
Ijesha.	Esa-Oke, Iwara, Ejioro, Odo Ibokun, Esa-Odo, Ijeda, Ikeji Ibala, Odo.
Ondo ati Eti Odo.	Igbo-Egunren, Atijere, Oni Ebiwo.
Egbado.	Idi-Emi, Ibese, Lasilọ, Atta.
Ogbomoshọ	Oko
Ekiti.	Ifaki.

ỌJỌ AJE 9TH MARCH (MONDAY)

Ilu.	Oruko Awon Oja.
Eko ati Agbegbe re Abeokuta.	Oyingbo. Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi
Ibadan.	Olode, Ogunjana, Lagun, Orile-Imo.
Ijebu.	Aiyepe, Sagamu, Ita-Osu, Ogere
Ijesha.	Imodi, Ita-Aganda, Oru-Awa. Iroiu, Ita-Iloti, Itele, Oyingbo Ijebu-Ijesha, Ibodi, Ibode
Ondo ati Eti Odo.	Kajola, Oluwa'da, Imesi-Ile Abigi, Aiyetoro, Oka, Ilara, Epe Ile-Oluji
Egbado.	Alagba, Ilaro, Sunwa, Iboro.
Ogbomoshọ	Obada, Gambari.
Ekiti.	Ilogbo, Oke-Aiyedun, Idogun,
Ibinni.	Ishan, Eke.

Enia meta ku ninu ijamba moto

ILORIN.

NI aro ojo Isegun ti ise ojo ketadinlogun osu yi ni moto-akeru kan LC9213 ti awamoto kan ti o nje Sunday nwa lo si Kano lati Eko pelu eru obi mesan ati awon ero ti o fere to ogbon enia sesi kolu gada Amilegbe leba Ilorin o si takiti lojiji sinu odo, o si baje koja atunse.

Enia meta ni o ku lesekese ti ijamba yi sele, oruko okan ninu won nje Abdulai Gasiki ti o ndari bo lati Ipinle Faranse, nwon ti ko awon mokanla ti o farapa pupoju ninu awon ero na lo si Ile-Iwosan-nla Ilorin, awamoto paapa na wa ni aye bi-yio-ku bi yio ye ni Ile Iwosan niaisiyi. Oruko eniti o ni moto ti o se ijamba na ni Ogbeni S. E. Oyeneye ti o ngbe 90, Simpson Street, I'Ebute Metta I'Eko.

Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun

AGBARA TITUN FUN AWỌN ỌKUNRIN

Ti o ba re o pupo ju, ti o ngbon riri lati agbara mo—pada o si odo awon opo eniz ti nwon nyo ti nwon ni agbara ati okun-inu nipa lilo VI-TABS Ni awon ile-itaja ogun ijetisi wa fun VI-TABS pe yo tun o se yio si jeki o ni lera.

IKỌ-FEE

TI I DI ỌNA-OFUN ỌJỌ KANNA NI YIO DẸ

Mase jeki iko-hihu, sinsin, didi ona ofun ti ikolu. Iko otutu tabi iko-fee ti ojo kan tabi oru ojo kan ba ofun tabi agbara ilera re je laiko dan MENDACO wo. Egbogi nla-nla yi ki ise eefin, aberẹ-gigun tabi fifun, sugbon ninu ọjọ ni o nise, bayi ni o ti se de inu edoforo ati awon iho-ona-ofun. Akolo re yio bere si ran ara lowo lesekese ni ona meta: Ekini yio se iranlowo a ti de kẹlẹbe kiki ti o nfun o lorun, yio si yo o kuro. Ekeji Bayi ni yio si fun o ni anfani mimi kale ati pelu irorun pelu orun asunwora. Eketa O nse iranlowo dide-iko, mimi tiotipa ati alsin. A se ileri itelorun ninu lilo re tabi si o gba owo re pada. Ra MENDACO lowo apoogun loni.

CLASSIFIED ADVERTISEMENT

FOR SALE

TYPEWRITERS — from £19
Ask catalogue T. E. C. 36, Goodge St, London W. 1.

BEECHAM'S POWDERS

Egbogi Otutu, Ayokele ati Iba

ti England nta pojulo

NISISIYI O wa ni NIGERIA

Bi o ba sin, tabi ti o ngbon, tabi ti ona pfun ba ndun e...

po Iyefun Beecham kan mo omi ki o si mu u.

We a tete gbadun.

BEECHAM'S POWDERS

egbogi *pataki fun* otuto, ayokele ati iba.

Olawoyin tu asiri ete Egbe Olomi lati di Egbe Afenifere lowo idibo

ILORIN.

NI ojo Ojobo ti ise ojo kerindinlogbon osu ti o koja yi ni Ogbeni J. S. Olawoyin, Akowe-agba Eka Egbe Afenifere (Action Group) Ipinle Ariwa ati Asoju Offa ninu Igbimo Ijoba Ipinle Ariwa so ninu ipade ti awon oniwe-irohin se ni Ilorin pe, awon Igbimo Iriju Egbe Olomi (NPC) ti ise Alamojuto Igbimo Ijoba Ibile Ilorin npete kan ninu Ipade Egbe Olomi Ilorin ati ti Offa ti nwon se ni Ilorin ni ojo 'Ru ti ise ojo kedogbon osu ti o koja yi pe, awon yio da rukerudo sile ni Offa lati dibo yan awon asoju wole Igbimo Apapo Ijoba Naijiria.

Ogbeni Olawoyin si tun so wipe, ninu ipade yi ni awon Egbe Olomi (NPC) ti yan Mustapha Keji ni Bale Offa titun dipo Oba Wuraola Isioye, Oloja Offa ti Ijoba Ipinle Ariwa daduro lori oye ninu odun 1957. O ni nwon si tun pinnu nibe pe, o to ki awon yan Oloja titun miran "lati le fa awon ara Offa sinu ariyanjiyan" nigbati ariyanjiyan ba si bere, awon y'o r'aye ko awon asiwaju Egbe Afenifere (Action Group) Ekun Ilorin timole.

Ogbeni Olawoyin se alaye pe, gegebi ero awon Egbe Olomi (NPC) fi oloja ko awon asiwaju Egbe Afenifere (Action Group) ati on paapa, yio ko idaru-dapo pupo ba eto Egbe Iselu on ni Ipinle Ariwa. Olawoyin tun la a ye ipade na pe, awon Egbe Olomi (NPC) ti menu ba eto a ti yan Oloffa titun miran ninu ipade ti awon Alamojuto Igbimo Ijoba Ibile Ilorin se ni ojo 'Ru ti ise ojo kedogbon osu ti o koja yi, nwon si ye ojo siso oro lori re si ojo keta osu yi pe, ni ojo na ni awon yio fi ipinnu si i.

Ogbeni Olawoyin si se alaye siwaju pe, awon Egbe Olomi (NPC) fi oro ti nwon so yi pe nkan isedale ati asa awon ara Offa ni ija ni, o si ke pe gbogbo awon omo Naijiria ti o ba nfe Ijoba rere pe, ki nwon mase mu oran na ni erebe, o si tun fi ti Oloja Ora ti Ijoba Ipinle Ariwa ro loye se apejuwe pe, ki nwon ba le je Bale Egbe Olomi (NPC) kan dipo re ni.

Ni ipari oro Ogbeni Olawoyin, o tokasi iwe kan ti Igbimo Ijoba Ibile Ilorin ko, ti Oba Ilorin si fowo si i ninu odun 1957, eyiti nwon fi nso fun gbimo Ijoba Ibile Offa pe, ki nwon yan Bale miran eyi ti yio wu awon ara Offa.

Adajo ju ajomogbe s'ewon odun meje

IJEBU-ODE.

NI ojo Ojobo ti ise ojo kerindinlogbon osu ti o koja yi ni Adajo Agba Kotu Ganran Ijebu-Ode ju Sunmola Okuyemi, eni odun marundinlogota ti o nsise agbe si ewon odun meje nitoripe o jebi ejo ti awon oloja ba se pe, o ji Fausatu Modiu, omo odun meji gbe ni Abule Irewon ni ogbonjo osu keta odun ti o koja yi.

Safu Modiu, iya omo na so fun Adajo na pe, ni ojo ti odaran na ji omo on gbe on nse onje lowo ni ile miran, omo on si nsere ni ita ile na. Iya omo na ni, nikehin on ko ri omo on mo ni on ba fi lobosi.

Aiyebukola onise gbena-gbena ti o tun wa jeri tako odaran na so fun Adajo na bi o nti se ri odaran na mu pelu omo na lowo re nigbati o ti rin to ibuso meji si abule kan ti o wa leba titi ona Ijebu-Ode. O ni laipe ti on ti ri i mu ni oloja de ba awon nibe, nwon si fi moto ayokele (taxi) kan gbe odaran na lo si Tesan

Igbeyawo omo Akintola

Lati oju ewe kini

enia pataki-pataki nwon si se eye na nibe titi ile fi su.

Ogbeni Loya Olusoji Atanda Odunjo ti ise oko iyawo na ni omo Oloye J. F. Odunjo ti Abeokuta, ninu awon ogunlogo enia ti o ba won lo si ibi igbeyawo na ni ilu Oyinbo lohun ni Oloye M. S. Sowole ti ise Asoju Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria fun ilu Oyinbo.

Fun lilo larin ilu tabi mimulo idale

VELOSOLEX

Agbara ti o nran keke-ologere lowo pelu awon anfani wonyi—didara lewa, alope pupo, ise ise daradarajulo ati ni owo pooku. Velosolex ki i pariwo, o si rorun lati ko ni ijanu. Yio gba o kale lowo a nwa moto wo.

£36 pere ni owo re

Ra Veloslex kan loni! ki o si ma a gbadun ise re fun opolopo qdun. Lo ba won se adehun rira abi hihaya ni ile ita moto C.F.A.O. ti o wa laroogto. Awon eya ara re wa nibe nigbakugba.

RANTI!
IRIN IBUSO VELOSOLEX KAN KO NA E TO KOBO KAN!
KOWE, FONU TABI KI O WA SI

C·F·A·O Velosolex Division
74 MARINA, LAGOS Telephone No. 23716

Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 3/7, Apongbon Street, Lagos. (Editorial and Advert offices). Telephone 23676. Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan: Eko—ale mejo ati kobo mejo (8s 8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun—ale metala (13s.). Olotu A. M. Ademuyiwa, 9, Chapel Street, Lagos.

Ę ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun